15. Ẹ kiyesi i, ki ẹnikẹni máṣe fi buburu san buburu fun ẹnikẹni; ṣugbọn ẹ maa lépa eyi ti i ṣe rere nigba gbogbo, laarin ara yin, ati laarin gbogbo eniyan. (Rom 12:17; 1 Pet 3:9; Gal 6:10; 2:13,14; Rom 14:9.)
16. Ẹ maa yọ̀ nigbagbogbo. (Filp 4:4.)
17. Ẹ maa gbadura ni àìsinmi.
18. Ẹ maa dupẹ ninu ohun gbogbo: nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun ninu Kristi Jesu fun yin.
19. Ẹ má ṣe pa iná Ẹmi. (Ef 4:30.)
20. Ẹ má ṣe kẹ́gàn isọtẹ́lẹ̀.
21. Ẹ maa wadi ohun gbogbo dájú; ẹ di èyí tì o dara mú ṣinṣin. (1 Kor 14:29; 1 Jhn 4:1.)
22. Ẹ maa takete si ohun gbogbo ti o jọ ibi.

**Ọ̀rọ̀ ìparí.**

23. Ki Ọlọrun alaafia tikararẹ sọ yin di mímọ́ patapata; ki a si pa ẹmi ati ọkan ati ara yin mọ́ patapata ni àìlábùkù ni ìgbà wiwa Oluwa wa Jesu Kristi. (Rom 15:33.)
24. Ọlododo ni ẹni ti o pè yín, ti yoo sì ṣe e. (1 Kor 1:9.)
25. Ará, ẹ maa gbadura fun wa. (Ef 6:19.)
26. Ẹ fi ifẹnukonu mímọ́ ki gbogbo awọn ará.
27. Mo fi Oluwa mu yin bura pé, ki a ka iwe yìí fun gbogbo awọn ará. (Kol 4:16.)
28. Ki oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi wà pẹlu yin. Amin.

53

# AWỌN ARÁ TESSALONIKA KEJI

**(A.D. 54)**

ORI 1.

**Ọro Ikini.**

PAULU, ati Silfanu, ati Timoteu, sí ijọ Tessalonika, ninu Ọlọrun Baba wa ati Jesu Kristi Oluwa : (1 Tess 1:1; 2 Kor 1:19; A.A. 16:1.)
2. Oore-ọfẹ si yin, ati alaafia, lati ọdọ Ọlọrun Baba, ati Jesu Kristi Oluwa. (Rom 1:7; 1 Kor 1:3.)

**Idupẹ.**

3. Iṣẹ wa ni lati maa dupẹ lọwọ Ọlọrun nigbagbogbo nitori yin, ara, ani gẹgẹ bi o ti yẹ, nitori pe igbagbọ yin ndàgbà gidigidi, ati ìfẹ́ olukuluku yin gbogbo sí ara yin ndi púpọ̀; (1 Tess 1:2; 3:12.)
4. Tobẹẹ ti awa tikarawa nfi yin ṣògo ninu ijọ Ọlọrun, nitori suuru ati igbagbọ yin ninu gbogbo inúnibíni ati wàhálà yin ti ẹyin nfaradà. (2 Kor 7:14; 1 Tess 1:3; 2:14.)

**Ìyànjú lati farada ìjìyà.**

5. Eyi ti i ṣe àmì idajọ ododo Ọlọrun ti o dájú, ki a lè kà yin yẹ fun ijọba Ọlọrun, nitori eyi ti ẹyin pẹlu ṣe njìyà: (Filp 1:28; 1 Tess 2:14.)
6. Bi o ti jẹ pe ohun òdodo ni fun Ọlọrun lati fi ipọnju gbẹ̀san lara awọn ti npọ́n yín loju. (Kol 3:25; Ifh 6:10.)
7. Ati fun ẹyin, ti a npọ́n loju, isinmi pẹlu wà, nigba ifarahan Jesu Oluwa lati ọrun wá ninu ọwọ́ iná pẹlu awọn angẹli alagbara rẹ̀. (1 Tess 4:16; Jud 14.)
8. Ẹni ti yoo san ẹ̀san fun awọn ti kò mọ Ọlọrun, ti wọn kò si gba ihinrere Jesu Oluwa wa gbọ: (Rom 2:8; Gal 4:8.)
9. Awọn ẹni ti yoo jìyà iparun ainipẹkun lati iwaju Oluwa wa, ati lati inu ogo agbara rẹ̀. (Filp 3:19; 2 Pet 3:7; 2 Tess 2:8.)

10. Nigba ti o bá dé lati jé ẹni ayìn-logo ninu awọn eniyan mimọ rẹ̀, ati ẹni iyanu ninu gbogbo awọn ti o gbagbọ (nitori a ti gba ẹ̀rí ti a jẹ fun yin gbọ) lọjọ naa. (Jhn 17:10; 1 Kor 3:13; 1:6.)

**Adura.**

11. Nitori eyi tí awa pẹlu ngbadura fun yin nigbagbogbo, pe ki Ọlọrun wa lè kà yín yẹ fun ìpè yin, ki o lè mu gbogbo ifẹ ohun rere ati iṣẹ igbagbọ ṣẹ nipa agbara rẹ̀. (ẹsẹ 5; 1 Tess 1:3.)

12. Ki a lè yin orukọ Jesu Oluwa wa logo ninu yin, ati ẹyin ninu rẹ̀, gẹgẹ bi oore-ọfẹ Ọlọrun wa ati ti Jesu Kristi Oluwa. (Filp 2:9.)

## ORI 2.

**Awọn iṣẹlẹ ṣaaju ọjọ́ Oluwa.**

SUGBỌN awa nbẹ̀ yín, ará, nitori ti wiwa Jesu Kristi Oluwa wa, ati ti ìpéjọpọ̀ wa sọdọ rẹ̀, (1 Tess 4:15–17; Mk 13:27.)

2. Ki ọkan yin maṣe tètè mì, tabi ki ẹ maṣe jáyà, yálà nipa ẹ̀mí, tabi nipa ọ̀rọ̀, tabi nipa ìwé bi lati ọdọ wa wá, bi ẹni pe ọjọ́ Oluwa dé. (1 Kor 1:8; Ef 5:6; 2 Tess 3:17.)

3. Ẹ maṣe jẹ ki ẹnikẹni tàn yin jẹ lọnakọna; nitori pe ọjọ naa ki yoo de, bikoṣe pe iyapa kuro ninu otitọ ba kọ́-kọ́ de, ati ki a sì fi ẹni ẹ̀ṣẹ̀ hàn, ti i ṣe ọmọ ègbé; (Dan 7:25; Jhn 17:12; Ef 5:6–8; Ifh 13:5.)

4. Ẹni ti nṣòdì, ti o si ngbe ara rẹ̀ ga si gbogbo ohun ti a npe ni Ọlọrun, tabi ti a nsìn; tobẹ̃ ti o jokòó ni tẹmpili Ọlọrun, ti o nfi ara rẹ hàn pe Ọlọrun ni oun. (Isa 14:13,14; Esk 28:2; 1 Kor 8:5.)

5. Ṣe ẹyin kò ranti pé nigba ti mo wà lọdọ yin, nkan wọnyìí ni mo sọ fun yin?

6. Ati nisinsinyìí ẹyin ti mọ ohun ti o ndá fifi hàn rẹ̀ ni akoko rẹ̀ duro.

7. Nitori pé ohun ijinlẹ ẹ̀ṣẹ̀ ti nṣiṣẹ́ ná: kìkì pé ó di igba ti eyi ti ndáa duro báyìí bá kuro nibẹ (Dan 7:25, 26; Ifh 17:5,7.)

8. Nigba naa ni a o si fi ẹni ẹ̀ṣẹ̀ naa hàn, ẹni ti Oluwa yoo fi ẹ̀mí ẹnu rẹ̀ pa, ti yoo si fi ifihan wiwa rẹ̀ sọ di asán: (Dan 7:10; Ifh 19:15.)

9. Ani oun, ẹni ti wiwa rẹ̀ yoo ri gẹgẹ bi iṣẹ Satani pẹlu agbara gbogbo ati àmì ati iṣẹ-iyanu èké. (Matt 24:24; Jhn 4:48.)

10. Ati pẹlu ìtànjẹ àìṣododo gbogbo fun awọn ti nṣègbé; nitori ti wọn kò gba ifẹ otitọ ti à bá fi gbà wọ́n là. (1 Kor 1:18.)

11. Ati nitori èyí, Ọlọrun ran ohun ti nṣiṣẹ ìṣìnà si wọn, ki wọn baa lè gba èké gbọ́: (Matt 24:5; Rom 1:28; 1 Tim 4:1.)

12. Ki a lè ṣe ìdájọ́ gbogbo awọn ti kò gba otitọ gbọ́, ṣugbọn ti wọn ni inu dídùn ninu àìṣododo. (Rom 1:32.)

**Idupẹ ati Ọ̀rọ̀ Iyanju.**

13. Ṣugbọn iṣẹ wa ni lati maa dupẹ lọwọ Ọlọrun nigbagbogbo nitori yin, ará, olufẹ nipa ti Oluwa, nitori lati àtè-tèkọ́ṣe ni Ọlọrun ti yàn yín sí igbala ninu ìsọdimímọ́ Ẹmi ati igbagbọ otitọ: (Ef 1:4; 1 Pet 1:2.)

14. Eyi ti o ti pè yin sí nipa ihinrere wa, ki ẹyin lè gba ogo Jesu Kristi Oluwa wa. (1 Pet 5:10.)

15. Nitori naa, ara, ẹ duro ṣinṣin, ki ẹ sì di ìlànà-ẹkọ́ wọnyìí mu ti a ti fi kọ yin, yala nipa ọ̀rọ̀, tabi nipa ìwé wa. (1 Kor 16:13; 11:2.)

16. Njẹ ki Jesu Kristi Oluwa wa tikararẹ, ati Ọlọrun Baba wa ẹni ti o ti fẹ wa, ti o ti fi ìtùnú ainipẹkun ati ireti rere nipa oore-ọfẹ fun wa, (Jhn 3:16; 1 Tess 3:11.)

17. Ki o tu ọkàn yin ninu, ki o si fi ẹsẹ̀ yin mulẹ ninu iṣẹ ati ọ̀rọ̀ rere gbogbo. (1 Tess 3:3; 1 Kor 1:8.)

## ORI 3.

**Paulu rọ awọn eniyan ki wọn maa gbadura fun wọn.**

LAKOTAN, ara ẹ maa gbadura fun wa, ki ọ̀rọ̀ Oluwa lè maa sare ki o si jẹ àyìn-lógo, ani gẹgẹ bi o ti ri lọdọ yin. (1 Tess 4:1; 5:25; 1:8.)

2. Ati ki a lè gbà wá lọwọ awọn aṣòdì ati awọn eniyan buburu: nitori pe ki i ṣe gbogbo eniyan ni o gbàgbọ́. (Rom 15:31; 1 Kor 1:9; 1 Tess 5:24; 2 Pet 2:9.)

3. Ṣugbọn olododo ni Oluwa, ẹni ti yoo fi ẹsẹ̀ yin mulẹ, ti yoo si pa yin mọ kuro ninu ibi. (1 Kor 1:9; 1 Tess 5:24; 2 Pet 2:9.)

4. Awa si ni igbẹkẹle ninu Oluwa niti yin, pé nkan wọnyìí ti a palaṣẹ fun yin ni ẹyin nṣe ti ẹ o si maa ṣe. (2 Kor 2:3; Gal 5:10.)

5. Ki Oluwa si maa tọ́ ọkan yin sinu ifẹ Ọlọrun, ati sinu suuru Kristi. (1 Kro 29:18.)

6. Awa si paṣẹ fun yin, ni orúkọ Jesu Kristi Oluwa wa, ki ẹyin yẹra kuro lọdọ olukuluku arakunrin, ti nrin ségesège, ti kì í ṣe gẹgẹ bi ìlànà-ẹ̀kọ́ ti wọn ti gba lọwọ wa, (1 Kor 5:4,11; 2 Tess 2:15.)

7. Nitori ẹyin tikara yin mọ̀ bi o ti yẹ ki ẹyin maa farawe wa; nitori awa kò rin ségesège laarin yin; (1 Tess 1:6.)

8. Bẹẹ ni awa kò si jẹ ounjẹ ẹnikẹni lọ́fẹ̀ẹ́; ṣugbọn ninu aápọn ati làálàá ni a nṣiṣẹ lọsan ati loru, ki awa má baa derùpa ẹnikẹni ninu yin: (A.A. 18:3; Ef 4:28; 1 Tess 2:9.)

9. Ki i ṣe pe awa kò ní agbara, ṣugbọn awa nfi ara wa ṣe apẹẹrẹ fun yin ki ẹyin lè maa farawé wa. (1 Kor 9:4.)

10. Nitori nigba ti awa tilẹ wà pẹlu yin, eyi ni awa pa laṣẹ fun yin, pe bi ẹnikẹni ko ba fẹ́ ṣiṣẹ́, ki o maṣe jẹun. (1 Tess 4:11.)

11. Nitori awa gburo awọn kan ti nrin ségesège laarin yin ti wọn kò ṣiṣẹ́ rárá, ṣugbọn wọn jẹ alátojúbọ̀. (1 Tim 5:13.)

12. Njẹ iru awọn ẹni bẹẹ ni awa npàṣẹ fun, ti a si nrọ̀ ninu Oluwa Jesu Kristi, pé ki wọn maa fi iwa pẹlẹ ṣiṣẹ, ki wọn sì maa jẹ ounjẹ awọn tikara wọn. (1 Tess 4:1,11; Ef 4:28.)

13. Ṣugbọn ẹyin, ará, ẹ maṣe ṣaarẹ̀ ni rere ṣiṣe. (Gal 6:9.)

14. Bi ẹnikẹni kò bá sì gba ọ̀rọ̀ wa gbọ̀ nipa ìwé yìí, ẹ sàmì si oluwarẹ, ki ẹ má sì ṣe baa kẹgbẹ, ki oju lè ti i. (Matt 18:17.)

15. Sibẹ ẹ maṣe ka a si ọ̀tá, ṣugbọn ẹ maa gba a niyanju bi arakunrin. (Gal 6:1; 1 Tess 5:14.)

**Adura, ìkíni ati oore-ọfẹ.**

16. Njẹ ki Oluwa alaafia tikararẹ̀ maa fun yin ni alaafia nigbagbogbo lọna gbogbo. Ki Oluwa wa pẹlu gbogbo yin. (Rom 15:33; Rut 2:4.)

17. Emi Paulu, ni o kọ ìkíni yìí ni ọwọ́ ara mi. Eyi sì ni àmì ninu gbogbo iwe mi; bẹẹ ni mo nkọ̀wé. (1 Kor 16:21.)

18. Oore-ọfẹ Oluwa wa Jesu Kristi kí ó wà pẹlu gbogbo yin. (Amin.) (Rom 16:20; 1 Tess 5:28.)

54

# TIMOTEU KINNI

**(A.D. 65)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ikini.**

PAULU, Aposteli Kristi Jesu, gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun Olùgbàlà wa, ati Kristi Jesu ireti wa; (A.A. 9:15; Kol 1:27.)

2. Si Timoteu, ọmọ mi tootọ́ ninu ìgbàgbọ́: Oore-ọfẹ aanú, alaafia lati ọdọ Ọlọrun Baba wá, ati Kristi Jesu Oluwa. (A.A. 16:1; 2 Tim 1:2.)

**Ìṣòro ti o wà ni Efesu; Ẹ̀kọ́ ti kò fẹsẹ̀múlẹ̀.**

3. Bi mo ti gbà ọ́ niyanju lati jokòó ni Efesu, nigba ti mo nlọ si Makedonia,